**O W E**

OKU eşinşin mu ororo ikunra olorun didun baję ki o ma fi run oorun didun mọ. Bęni were diẹ wuwo ju ọgbọn ati ọla lọ.

# Irohin Yoruba

NO. 805. NOVEMBER 9 — NOVEMBER 15, 1960 Kobo Meji (2D.)



O dara pupọ fun Ikọ ti o nyọ awọn ẹbi rẹ lẹnu
O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# ỌBA AGURA W'AJA



**Aworan *yi* ni ti ologbe Ọba Alaiyeluwa Shobẹkun Keji, Agura Gbagura, Abẹokuta. Ka itan igbesi aiye ologbe Ọba na ni oju ewe Kejila.**

# Ominira Ilẹ Naijiria (3)

*( Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande I, Ogbomọshọ )*

ALAYE kẹta ti a o ṣe nipa Ominira ilẹ wa, ẹsẹ wura ọrọ wa na ni ọrọ ti a sọ ninu Kọrinti keji ori 3, ẹsẹ 17, bayi pe, "Nibiti Ẹmi Oluwa ba wa, nibẹ ni Ominira gbe wa.' Ọrọ yi nsọ fun wa pe ki a to le gba pe a ni ominira totọ, a fi bi Ẹmi Oluwa ba mbẹ ninu wa, nigbana ni a ki yio sọ ominira na di INIRA.

O yẹ ki ọrọ na ye gbogbo wa daradara, awa gẹgẹbi awọn ọba ilẹ wa awọn minista wa, awọn ọlọla wa, awọn alaṣẹ ilẹ wa, gbogbo awọn oniṣẹ Ijọba ilẹ wa, ati olukuluku wa gẹgẹ bi ọmọde ati agba,, o yẹ ki o ye wa, ki a si gba pe, dajudaju, nibiti Ẹmi Oluwa ba wa nibẹ ni ominira gbe wa pẹlu.

**OMINIRA-INIRA**

Awọn orilẹ-ede ti Ẹmi Oluwa ko si ninu wọn, nigbati nwọn gba ominira wọn, inira patapata lo da mọ wọn lọwọ, ti nwọn bẹrẹsi pa ara wọn, ti nwọn si nle ara wọn jade kuro ni ilu. Oluwa ko ni jẹki ominira tiwa di inira fun wa o. Amin.

Bi Ẹmi Oluwa ba wa ninu wa, apẹrẹ iru iwa ti a o ma a hu, ti ominira na yio si jẹ itura fun orilẹ-ede wa ni iru ọrọ ti a ri ka ninu Luku 9: 51-56, bayi pe, "Nigbati Jesu Kristi pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ nlọ si Jerusalẹmu, nigbati nwọn de ileto awọn ara Samaria, nwọn ko gba wọn ni alejo rara, nitoripe awọn ara Samaria korira awọn ero."

"Nigbana ni awọn ọmọ-ẹhin Jesu wi fun Jesu pe "Oluwa, jẹki a pe ina lati ọrun wa, ki a sun wọn lulu gẹgẹ bi Elijah ti ṣe' ṣugbọn Jesu yipada, o si ba won wi, o wipe, 'Ẹnyin ko mọ iru Ẹmi ti mbẹ ninu nyin, nitori ọmọ-enia ko wa lati pa ẹmi enia run, bikoṣe lati gba a la."

**ẸMI OLUWA**

Eyi fihan pe Ẹmi Oluwa ki ṣiṣẹ iparun, Ẹmi Oluwa ki iṣe ika, Ẹmi Oluwa a ma a mu suru fun ẹlẹṣẹ, Ẹmi Oluwa ki ida enia loro, Ẹmi Oluwa ki pa enia l'ẹkun, dajudaju bi gbogbo wa ba kun fun Ẹmi Oluwa, ominira yi yio jẹ itura ati alafia fun gbogbo wa.

Apẹrẹ keji ni igbati agbara wa lọwọ Josẹfu Alala ni ilẹ Egipti nijọsi, ti awọn arakunrin rẹ ti o ta a si oko ẹru mbẹru pe bọya Josẹfu yio fi iya jẹ wọn lẹhin iku baba wọn, ṣugbọn Josẹfu ẹniti o kun fun Ẹmi Oluwa ko ṣe bẹ rara.

"Ṣugbọn ẹ gbọ ohun ti o sọ ninu Gen. 50: 19-20, bayi pe, 'Josẹfu si wi fun wọn pe: 'Ẹ maṣe bẹru, emi ha wa ni ipo Ọlọrun? ṣugbọn b'o ṣe ti nyin ni, ibi li ẹnyin ro si mi, ṣugbọn Ọlọrun mọ ọ si rere".

Dajudaju, Ẹmi Oluwa ni ko jẹki Josẹfu le ṣe awọn arakunrin rẹ ni iṣekuṣe, Ẹmi Oluwa lo mu ki o dariji wọn.

Nisisiyi, Ijọba ilẹ wa ti bọsi ọwọ ara wa, o ku sọwọ ẹnyin alaṣẹ ilẹ wa lati lo aṣẹ na daradara, ẹ maṣe lo o ni ọna ti awọn enia yio fi ma ke abamọ, ẹ maṣe lo ida ominira na lọna ti awọn enia yio fi ma a wipe, "Ijọba ti awọn Oyinbo tura ju tiwa yi lọ".

Ẹ jẹki ọrọ Josẹfu ma a wa lọkan nyin nigba gbogbo pe 'Ki iṣe ipo Ọlọrun ni ẹ wa". Ọlọrun nikan ni ayipada ko le de ba. Ẹ fi Ẹmi Oluwa lo ida ominira na lọna rere ki ẹ pẹ ninu ipo giga na ti a fi le nyin lọwọ.

Gbogbo wa gẹgẹbi ọmọ ilẹ Naijiria, ninu ipo ti olukuluku wa ba wa, ati nipa orisirisi ida ti o wa lọwọ wa, ẹ jẹki a kun fun Ẹmi Oluwa, ki a si ma a fi ti Ọlọrun ṣaju gbogbo ero wa, ki Ominira yi le jẹ itura, alafia ati ibukun fun gbogbo wa.

Ẹ ku ayọ ominira, ṣugbọn ẹ maṣe gbagbe otitọ na ti a sọ fun wa ninu Kọrinti keji ori 3, ẹsẹ 17, bayi pe, "Nibiti Ẹmi Oluwa ba wa, nibẹ ni OMINIRA gbe wa." Ẹ ku igbadun OMINIRA.


Ni ikẹhin— IWOSAN FUN RORẸ ATI OORU-ARA-SISU

Nisisiyi, awọ-ara rẹ yio mọ gara yio si jọlọ pada! Ni ikẹhin, egbogi kan niyi ti o le wo gbogbo rorọ ati ooru-ara-sisu san patapata.



Egbogi Agbarun

VINOLIA

IYẸFUN EGBOGI RORẸ ATI OORU-ARA-SISU

— ti awọn Dọkita nlo

VINOLIA RỌRUN PUPỌ LATI LO PẸLU

Lẹhin ti o ba ti fi ọṣẹ ati omi wẹ ara tan, fi ọpọlọpọ iyẹfun egbogi na kun ibiti o ba ndun ọ ni ara rẹ dada. Lo iyẹfun na bi o ti wu ki o ri lẹkan lọsan ati lẹkan lalẹ. Ni ọjọ kini kikan rẹ yio rọlẹ, ni ọjọ keji, awọn rorẹ yio gbẹju, ati ni ọjọ kẹta ati ẹkẹrin gbogbo wọn yio jinna nwọn yio si parẹ.



Iyẹfun egbogi Vinolia fun ooru-ara-sisu ni iyatọ diẹ ni ara si iyẹfun egbogi agbarun lasan, ṣugbọn idi eyi ni pe, nitoripe o jẹ egbogi ni.



RALEIGH 'Popular'

Ndan yanranyanran pẹlu agbara didara Raleigh

Oju iyin ni yio tẹle ọ nibikibi nigbati o ba gun Basikulu Raleigh "POPULAR" Enikeni yio yin ọ fun ọgbọn ti o fi yan basikulu ti o dara. Basikulu Raleigh "Popular" a ma a tan itanṣan a si ma a dan yanranyanran pẹlu ẹṣọ-ọda Raleigh ti gbogbo enia mọ. yio si ṣiṣẹ atata fun ọ fun ọpọlọpọ ọdun ni gigun pẹlu faaji ati irọrun. Ko si basikulu ti a le fi we Raleigh fun agbara ati ṣiṣẹ rẹ! Bere lọwọ onibara basikulu rẹ pe ki o fi gbajumọ basikulu RALEIGH "POPULAR" han ọ.

Basikulu

IYATO TI O WA FUN RALEIGH "POPULAR"

AWỌN ẸLO-IRINṢẸ RALEIGH FUN O







RALEIGH

BASIKULU ONI GBOGBO-ARA KIKI IRIN-TUTU

Eyii o jade lati Ilẹ-Ìgẹ TITO IRINṢẸ RALEIGH ATATA ni Mushin, Eko.

STURMEY ARCHER

ANFANI IṢURA AWỌN OHUN ỌṢỌ

O le ra Basikulu "POPULAR" rẹ pẹlu "Sturmey Archer" oni-jia mẹta ti o njẹki basikulu rọrun ni gigun ni gbogbo ayekaye ati atupa "DYNOHUB". Bere lọwọ onibara Basikulu rẹ pe ki o fi agbayanu iṣura yi han ọ.

# ITUMỌ ALA

## Lati ọwọ Josẹfu Alala, Mushin

ẸKEJI ỌKỌ IYAWO—Ti o ba la ala pe ọrẹ re gbe iyawo ati wipe iwọ ni o ṣe ekeji rẹ nibi igbeyawo na, ṣọra gidigidi lasiko na ki o ma ba a padanu ohun ini rẹ ti o ṣọwọn fun ọ julọ.

TẸTẸ—ti o ba la ala pe o jẹ tẹtẹ, ki o to le jẹ yio pẹ pipọ, ṣugbọn ti o ba la ala pe o kuna iwọ ko ni pẹ jẹ.

ỌJỌ/IBI—Ti o ba la ala pe o nṣe ọjọ ibi tabi o wa nibiti nwọn ti nṣe ọjọ ibi,ifa airotẹlẹ ko ni pẹ wọle tọ ọ.

ẸIYẸ OGE—Ti o ba ri ẹiyẹ Oge loju ala ti o ba nkọrin, iwọ ko ni pẹ ṣe orire.

AFỌJU—Ti o ba la ala pe oju rẹ fọ lojiji tabi o ri ẹniti o fọju, ṣọra gidigidi ki o ma ba a sọ owo nu.

ẸJẸ—Ti o ba ri ẹjẹ loju ala yala o farapa ni o, tabi ẹlomiran ni o farapa, ṣọra ki o ma ba a k'agbako alajangbila ti yio wa ko tirẹ ba ọ.

EGUNGUN-ẸRAN—Ti o ba ri egungun ẹran loju ala ijangbọn ti o ko fọwọ fa ko ni pẹ di tirẹ.

ẸGBẸ IBUSUN—Ti o ba lala pe o duro lẹgbẹ ibusun ẹnikan ti o sun lọ, o si nṣọ ọ, iwọ ko ni pẹ gbọ iro aisan si ọrẹ rẹ tabi ẹbi rẹ lati ọna jinjin rere.

ỌTI—Ti o ba lala pe o ngmu ọti tabi o ri ẹniti o ngmu ọti, ṣọra gidigidi ki o ma ba a ṣe aisan lojiji.

OYIN—Ti o ba jẹ ẹniti o da iṣẹ ọwọ silẹ ala rere ni ti o ba si nṣiṣẹ labẹ enia, iwọ ko ni pẹ ri igbega lẹnu'ṣẹ, ohunkohun to ba si ṣe laseko yi, eyiti iba fi mu adanu wa rere ni yio jasi fun ọ.

Ọlọbọunbọun—Awọn ọrẹ ti o gbẹkẹle ko ni da ọ.

ODODO—Ti o ba lala pe o ri ododo ala rere ni, ohun rere ti o ba dawọle rere ni yio jasi, iwọ ko si ni ri elebu-ẹhin laseko na.

IGO—Ti o ba ri igo ofifo ni oju ala, ko dara rara, agbara awọn ọta rẹ yio ka ọ lati ṣe ọ ni ijamba, ṣugbọn ti igo na ba kun fun omi tabi epo, ohun rere ti o ti nwa lati ọjọ pipẹ yio tẹ ọ lọwọ.

ỌFA—Ti o ba ri tafatafa loju ala tabi iwọ paapa nta ọfa ti o si ba ohun ọdẹ rẹ gbogbo ero t'o nrọ lọkan rẹ, rere ni yio jasi, ṣugbọn ti ọfa na ba tase ohun ọdẹ na aibalẹ ọkan ati idarudapọ yio de ba ọ laseko na.

ỌDỌMỌKUNRIN—Ti o ba la ala pe o ri ọdọmọkunrin kan, ibanujẹ yio jinna si ọ laseko yi.

ẸGUN OṢUṢU—Ti o ba la ala pe ẹgun gun ọ lẹsẹ tabi o ri ẹniti ẹgun gun lẹsẹ, itumọ ala na ni pe ijamba ojiji mbọ.

IDẸ—Ti o ba la ala pe o ri idẹ ti o ndan yanranyanran, itumọ rẹ ni pe owo-ifa yio de fun ọ lati ọna jinjin rere, ti o ba si jẹ idẹ ti o dipẹta ni o ri, ṣọra ki o ma ba a padanu owo.

BURẸDI—Ti o ba ri ọpọlọpọ burẹdi loju ala, yala ẹnikan nta a ni, tabi o ri ni ile ti nwọn ti nṣe e, ohunkohun ti o ba dawọle paapa iṣẹ, iwọ yio ri ọpọlọpọ owo nibẹ.


## NIGERIAN RAILWAY CORPORATION

### *Atunṣe Eto Irin Ọkọ-Ero*

Bẹrẹ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kini oṣu kọkanla ọdun yi, gbogbo awọn ọkọ-ero ti o ba npada bọ wa si Eko yio duro ni Teṣan Ebute Mẹtta Junction lati jẹki awọn ero ti o ngbe ẹhin-odi Eko sọkalẹ kuro ninu ọkọ na.

Eto irin awọn ọkọ-ero igberiko larin Eko ati Idọgọ bẹrẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ keje oṣu kọkanla ọdun yi, ati ti Eko si Ọffa yio tun ni ilọsiwaju.

(a) Awọn ọkọ Idọgọ yio kuro ni Teṣan Eko ni agogo mẹrin irọlẹ ojojumọ (dipo ogogo mẹta ọsan), bi o ba si npada bọ wa si Eko, yio kuro ni Idọgọ ni agogo mẹta kọja iṣẹju mẹdọgbọn ọsan ni ojojumọ (dipo agogo mẹrin ku iṣẹju mẹdọgbọn ọsan).

(b) Awọn ọkọ-ero yio dide ni Ọffa wa si Eko ni agogo mẹjọ ku iṣẹju mẹtadilọgbọn arọ ojojumọ (dipo agogo marun idaji). Ọkọ na yio gunlẹ si Ibadan ni agogo mejila kọja iṣẹju marun ọsan yio si de Teṣan Eko ni agogo mẹjọ ku iṣẹju mejidilọgbọn alẹ ni awọn ọjọ lasan, yio si ma a de ni agogo mẹjọ alẹ awọn ọjọ Aiku.

Fun alaye siwaju, **bi ọga Teṣan Ọkọ adugbo rẹ lere.**

**Alafia wa ninu fifi ọkọ Reluwe rin irin-ajo**



# "CEMENT"




BSS. 12/1958

THE STRONGEST OF ALL

IT'S NIGERIAN PRODUCT OF HIGHEST QUALITY

FRESH FROM IT'S FACTORY

**EWEKORO WORKS**

MILE 40, ABEOKUTA ROAD.

You will be able to obtain supplies of this Highest Quality Cement

From:-

MESSRS **BREWACO** (NIGERIA)

**TRADING CO.**

11, Martins Street (3rd Floor)

P. O. Box 447 Telephone 25627,

**LAGOS, NIGERIA**

Please Telephone, Call or Write Us In Order to avoid Disappointment

## Akede Ọna Igbala

# Iwọ ha ti di ọmọ Ọlọrun nitotọ bi?

LONI a o sọ nipa ọjọ ti ohun kan ṣelẹ ninu ọdun 1517. Ọkunrin kan wa, ti a npe ni Martin Luther, ẹniti o jẹ akọwe daradara. Ogbẹni Luther ti ri nkan ti oniwasu kan nṣe, o dun un pupọ nigbati o mọ pe yio ba ogo Ọlọrun ati Ijọ Ọlorun jẹ.

O ti pese iwe kan ti o han si ara ilẹkun Ile Ọlọrun nibiti gbogbo awọn enia ni ilu yio ti le ri i ka. Awọn ọrọ iwe yi ba oniwasu buburu yi wi, nwọn si fi ọna ti o dara han fun awọn ti nwọn fẹ gba Jesu Kristi gbọ. Inu bi diẹ ninu awọn oniwasu si Ọgbẹni Luther, ṣugbọn ọpọlọpọ enia mọ pe ohun ti nwọn ṣe ko dara. Awọn enia nwọnyi yi ọkan wọn pada, nwọn si wa ọrọ Ọlọrun, lati mọ ifẹ Ọlọrun nipati ohun wọnyi. Eyi jẹ ibẹrẹ iyipada nlanla ti o ṣelẹ ninu Ijọ Ọlọrun.

**IYIPADA**

Loni, a nilati ri iyipada larin gbogbo Ijọ Ọlọrun wa. Bawo ni ṣọọṣi ti ṣe ma nkun to ni owurọ ọjọ ọsẹ? O ma nkun nitotọ melo ninu wa ni o ngmu Bibeli wa, ati iwe orin ati iwe adura wa lọ si Ile Ọlọrun?

Dajudaju a pọ bi a ti nṣe eleyi. Ṣugbọn melo ninu wa ni o ni Ọrọ Ọlọrun ninu ọkan wa ati ninu igbeaiye wa lojojumọ nibi gbogbo ti a nlọ? Melo ninu wa ni ayọ Kristi ngmu ki ọkan wa ma kọrin bi a ti nṣe iṣẹ wa lojojumọ? Efesu 5: 18-19 sọ bayi pe: "Ṣugbọn ẹ kun fun ẹmi ẹ si ma ba ara nyin sọrọ ninu Psalmu, ati orin iyin ati orin ẹmi ẹ ma kọrin ki ẹ si ma kọrin didun li ọkan nyin si Oluwa."

Ọpọlọpọ enia nlọ si ile Ọlọrun nitoripe nwọn ka a si ohun ti o dara lati ṣe. Nwọn fi ọrẹ fun Oluwa, ṣugbọn ki iṣe niti ifẹ ni nwọn ṣe eyi. Nwọn nronu boya Ọlọrun yio fun wọn ni nkan ti nwọn fẹ ninu aiye yi ati pe yio fun wọn ni iye ainipẹkun ninu ti mbọ.

Ọlọrun ko fẹ ẹbọ wa, igbọran ati ifẹ ni O fẹ. O nfẹ ki a fun On ni igbeaiye wa. "Oluwa ha ni inu didun si ọrẹ sisun ati ẹbọ bi pe ki a gba ohun Oluwa gbọ? Kiyesi i igbọran san ju ẹbọ lọ, ifetisilẹ si san ju ọra agbo lọ" (I Samueli 15: 22).

**APẸẸRẸ IFẸ**

Ko si anfani ninu wiwa si Ile Ọlọrun ki a ma gbe Bibeli wa ati iwe orin wa dani bi a ko ba mọ Ọlọrun, Ẹniti nwọn fi ba wa sọrọ, bi Ọrẹ wa totọ. Ọrẹ wa ko ni iye lori loju Ọlọrun, bi a ko ba fi apẹẹrẹ ifẹ wa han An lati sin I gẹgẹbi o ti yẹ Ọlọrun ko tilẹ le gbọ adura wa, nitori ẹlẹṣẹ ni wa, Ọlọrun ko si le wo ẹṣẹ 'Bi emi ba gba ẹṣẹ li aiye mi Oluwa ki yio gbohun mi." (Orin Dafidi 66: 18).

Ọna kanṣoṣo ti a le gba fi ṣe igbọran si Ọlọrun ni lati ni ọkan titun ti o mọ. Ẹṣẹ jẹ ṣiṣe ohun ti ko yẹ ki a ṣe, o si jẹ aiṣe ohun ti o yẹ ki a ṣe. Ko si ọna miran ti a le gba fi bọ lọwọ ẹṣẹ bikoṣe nipasẹ Jesu Kristi Ẹniti o ku fun wa lori Igi Agbelebu ti o si le wẹ ẹṣẹ wa gbogbo nu. "Ko sisi igbala lọdọ ẹlomiran nitori ko si orukọ miran labẹ ọrun ti a le fifunni ninu enia nipa eyiti a le fi gba wa la." Iṣe Awọn Aposteli 4: 12).

A nilati mọ pe awọn iṣẹ rere wa ko le gba wa la. Awọn ọrẹ wa ko to pẹlu ko si ohun kan ti o to bikoṣe ẹjẹ Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun. "Ẹjẹ Jesu Kristi Ọmọ Rẹ ni nwẹ wa nu kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (Johannu 1: 7). A nilati bẹ Ọlọrun ki O le dari ẹṣẹ wa ji wa, ki Jesu Kristi wẹ ẹṣẹ wa nu kuro li ọkan wa, ki O si le gba wa lọwọ agbara aṣẹ lati ṣe eyi nitoripe o ti jiya fun wa lori igi agbelebu.

Nigbati a ba gba gbogbo nkan wọnyi gbọ ti a si ti bẹ Olugbala wa ti yio wẹ ẹṣẹ wa nu, o yẹ ki a ba awọn ẹlomiran sọrọ nipati ohun iyanu yi. Dajudaju iyipada iyanu ni yio jẹ ninu ọkan wa nigbati Ọlọrun ba di Oluwa lori wa, nigbati ayọ rẹ ati alafia Rẹ ba kun ọkan wa. "Bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu li Oluwa, ti iwọ si gbagbọ li ọkan rẹ pe Ọlọrun ji i dide kuro ninu oku a o gba ọ la" (Romu 10: 9).

Nigbana bi a ti ndagba ninu igbagbọ, Ọlọrun yio lo wa ni ọna titun ninu Ijọ wa, nwọn yio si ni iyipada nwọn o si di onitara si ifẹ Ọlọrun, Ogo Ọlọrun yio si tan yi orilẹ-ede wa ka.

Ma ṣai jẹki ọjọ yi gan an jẹ ọjọ pataki fun ọkan rẹ. Ṣe ipinnu loni lati di ọmọ Ọlọrun totọ nipa gbigba Jesu Kristi Ẹniti O ku ki o le ni iye. "Ṣugbọn iye awọn ti o gba A, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun ani awọn na ti o gba orukọ rẹ gbọ" (Johannu 1. 12).






**Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"**

NJẸ O NI OTUTU IBA




# Itan iṣẹdalẹ ilu Ijẹbu-Ijẹsha

**(Lati ọwọ Alaiyeluwa Arojojoye Keji, Ọba Ijẹsha)**

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati sọ itan ilu mi Ijẹbu-Jẹsha ti o wa ni Ẹkun Ọyọ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria fun gbogbo awọn onkawe "Irohin Yoruba" kakiri gbogbo aiye ka. Itan mi na lọ bayi:—

Nigba iwaṣẹ, bayi ni idile iran Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti ṣe bẹrẹ ni ajule wọn ni Ile-Ifẹ: Oduduwa ni Baba Ọranmiyan, Ọranmiyan ni Baba Agigiri Kini, Agigiri Kini ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha, Ọranmiyan na ni o si bi Eweka Kini ni Ado-Binni

Ni igba lailai, obirin kan wa ni Ile-Ifẹ, orukọ rẹ njẹ Ijasin ni adugbo Ilode. Ijasin yi bi ọmọbirin mẹta, arẹwa enia si ni awọn mẹtẹta gẹgẹbi iya wọn.

**ORUKỌ WỌN**

Orukọ awọn mẹtẹta na niwonyi:—Ekini njẹ Ọmọrẹmi, ekeji njẹ Omutoto ẹkẹta si njẹ Pabiorunja. Ọranmiyan ọmọ Oduduwa fẹ Ọmọrẹmi ti o jẹ agba fun awọn ọmọ meji yoku, o fi ṣe aya.

Oduduwa ni Baba Ọlọfin, Ọlọfin na tun mu eyi atẹle ọmọ iya yi ti orukọ rẹ njẹ Omutoto fi ṣe aya, eyini ni pe, ọmọ Baba meji fẹ ọmọ iya meji, Ọmọrẹmi si bi Agigiri fun Ọranmiyan.

Lẹhin oṣu kẹta ti Ọmọrẹmi bi Agigiri fun Ọranmiyan tan, Omitoto aburo rẹ na si bi Ajibogun fun Ọlọfin. Nigbati o di oṣu kẹta ti Omutoto ti bimọ ni Omutoto ku, Ọmọrẹmi ẹgbọn Omitoto wa gbe Ajibogun ọmọ Omutoto, o si ntọju rẹ pẹlu ọmọ tirẹ, awọn mejeji si jijọ ndagba papọ.

Ajibogun yi ni Ọwa Ilesha Agigiri yi ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha, Ajibogun ati ẹgbọn rẹ Agigiri ni nwọn jijọ lọ tẹ ilẹ Ijẹsha do, ti onikaluku si ni ipinlẹ tirẹ.

**AALA ỌWA**

Yara-Igbo ni aala ilẹ Ọwa ati Ọba Ijẹbu-Jẹsha. ibusọ mẹta ni Yara-Igbo yi fi jinna si Afin Ọba Ijẹbu-Jẹsha. Lati Yara-Igbo yi ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti ni ilẹ titi fi de aala ilẹ Ijẹsha ati Ekiti.

Nigbati awọn mejeji tẹ Ijẹsha do tan, nwọn tun pada lọ si Ile-Ifẹ lati lọ ko awọn enia wọn wa. Ajibogun mu ọgbọn (30) enia, Agigiri na si mu ogun (20) enia, gbogbo awọn enia na jẹ adọta (50). Olukaluku si mu awọn enia tirẹ lọ si ori ilẹ tirẹ.

**IBOJI AGIGIRI**

Iboji Ọba Agigiri wa ni Afin Ọba Ijẹbu-Jẹsha, nibẹ si ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti nfi Ọwa Ilesha jẹ oye Ọwa titi di oni-oloni. Awọn ohun-ini Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti a le sọ diẹ ninu wọn niyi:

ITIMỌLE (Custody)—Iho ti nwọn nsọ alaigbọran sinu rẹ.

UGBERE (Prison Yard) Ọgba-ẹwọn tabi ibiti nwọn nko awọn arufin ti nwọn ti dajọ ẹwọn fun ni Oko-ọba.

Ọba Ijẹbu-Jẹsha nṣe idajọ fun apania. Igi Akoko ti Ọba Ijẹbu-Jẹsha fi npa awọn arufin ipania ṣi wa nibẹ titi di isisiyi.

Ọgba Ọba fẹ to ọgọta oṣuwọn eeka (60 acres)

Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn oloye tirẹ ti o nfi jẹ oye ni Afin rẹ. Awọn Ijoye rẹ ti o nfi jẹ oye ninu Afin rẹ to adọjọ (150). Ninu awọn Oloye wọnyi, awọn oloye obirin wa ninu wọn pẹlu.

(KOI TI PARI)

# Alapara Ibadan

ALAPARA—Ẹ o jire bi o? Olotu?

OLOTU—Alafia ni a wa o. Ṣe nipa ọrọ asọti wa ti ọsẹ ti o kọja ni o tun ba wa tabi o ni irohin aladun kan lati fun wa?

ALAPARA—Ọrọ asọti wa na wa ninu ohun ti mo ba wa si ọdọ nyin ṣugbọn nko ni ri aye to bẹ ẹ lati joko pẹ titi lọdọ nyin loni nitori mo ni idiwọ kekere kan.

OLOTU—Iru idiwọ wo ni o ni?



ALAPARA IBADAN

* * *

ALAPARA—Ija nla kan ni o ṣẹlẹ larin awọn ẹbi wa, ti mo si nilati joko pẹlu awọn agbalagba lati yanju rẹ.

OLOTU—Iru ija wo ni, tabi kini o fa ija na ti o fi ka ọ lara to bẹẹ ti o fi fẹ wa ninu ijoko atunṣe na.

ALAPARA—Bi mo ba pe ki nsọ idi ohun ti o fa ija na fun nyin yio dabi ẹniti nfẹ idi araẹni sita, nitori ọran larin ẹbi ni, ni bi abuku kan ba wa ninu ẹjọ riro wọn, nko ni le sọ fun araiye gbọ, bẹ ẹ bi mo ba sọ idi ija na fun nyin nisisiyi yio di irohin ti gbogbo aiye yio fẹ gbọ bi a ti pari rẹ si.

OLOTU—O dara o, emi na fi ara mọ ero rẹ nitoripe ibajẹ ọjọ kan ko tan ni ogun ọdun. Ṣe o ko ni pẹ ki a to tun ri ra o?

ALAPARA—Pipẹ kẹ! A ki i hun agbọn ki a ma ki eti ,rẹ emi ti mo bere ọrọ pataki lọwọ nyin ti mo si sọ pe mo fẹ idahun rẹ, ti ẹ ko si ti fun mi ni idahun rẹ ha le dakẹ laifori rẹ ti na ki a to mu omiran sọ.

OLOTU—Ṣe ọrọ ibere rẹ nipa pe ọti wo ni mo ngmu tabi iyen kọ?

ALAPARA—Iyẹn na ni! Ẹ sa mu suru ki ntun pada wa.

OLOTU—Ọwọ emi na di pupọ nisisiyi boya ti o ba tun pada wa nigbamiran, a a ma a sọ yẹn.

ALAPARA Ẹ ṣe pupọ o, o digba oṣe o.

OLOTU—Kabọ o, ipade wa bi oyin.

**Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"**


NJẸ O NI

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE

Nigbati o ba ni otutu-iba ti o ngbọnriri. tabi ẹfọri tabi ẹhin didun ati irora t'apa-t'itan, tabi sinsin. tabi ọgbẹ ọna-ọfun, mu koro "ASPRO" meji, otutu iba rẹ yio lọ, "ASPRO" ko lewu rara tabi ipalara fun ọkan "ASPRO" ni egbogi na gan an




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA


# Itan iṣẹdalẹ ilu Ijẹbu-Ijẹsha

## (Lati ọwọ Alaiyeluwa Arojojoye Keji, Ọba Ijẹsha)

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati sọ itan ilu mi Ijẹbu-Jẹsha ti o wa ni Ẹkun Ọyọ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria fun gbogbo awọn onkawe "Irohin Yoruba" kakiri gbogbo aiye ka. Itan mi na lọ bayi:—

Nigba iwaṣẹ, bayi ni idile iran Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti ṣe bẹrẹ ni ajule wọn ni Ile-Ifẹ: Oduduwa ni Baba Ọranmiyan, Ọranmiyan ni Baba Agigiri Kini, Agigiri Kini ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha, Ọranmiyan na ni o si bi Eweka Kini ni Ado-Binni

Ni igba lailai, obirin kan wa ni Ile-Ifẹ, orukọ rẹ njẹ Ijasin ni adugbo Ilode. Ijasin yi bi ọmọbirin mẹta. arewa enia si ni awọn mẹtẹta gẹgẹbi iya wọn.

**ORUKỌ WỌN**

Orukọ awọn mẹtẹta na niwọnyi:—Ekini njẹ Ọmọrẹmi. ekeji njẹ Omutoto ẹkẹta si njẹ Pabiorunja. Ọranmiyan ọmọ Oduduwa fẹ Ọmọrẹmi ti o jẹ agba fun awọn ọmọ meji yoku, o fi ṣe aya.

Oduduwa ni Baba Ọlọfin, Ọlọfin na tun mu eyi atẹle ọmọ iya yi ti orukọ rẹ njẹ Omutoto fi ṣe aya, eyini ni pe, ọmọ Baba meji fẹ ọmọ iya meji, Ọmọrẹmi si bi Agigiri fun Ọranmiyan.

Lẹhin oṣu kẹta ti Ọmọrẹmi bi Agigiri fun Ọranmiyan tan, Omitoto aburo rẹ na si bi Ajibogun fun Ọlọfin. Nigbati o di oṣu kẹta ti Omutoto ti bimọ ni Omutoto ku, Ọmọrẹmi ẹgbọn Omitoto wa gbe Ajibogun ọmọ Omutoto, o si ntọju rẹ pẹlu ọmọ tirẹ, awọn mejeji si jijọ ndagba papọ.

Ajibogun yi ni Ọwa Ilesha Agigiri yi ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha, Ajibogun ati ẹgbọn rẹ Agigiri ni nwọn jijọ lọ tẹ ilẹ Ijẹsha do, ti onikaluku si ni ipinlẹ tirẹ.

**AALA ỌWA**

Yara-Igbo ni aala ilẹ Ọwa ati Ọba Ijẹbu-Jẹsha. ibusọ mẹta ni Yara-Igbo yi fi jinna si Afin Ọba Ijẹbu-Jẹsha. Lati Yara-Igbo yi ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti ni ilẹ titi fi de aala ilẹ Ijẹsha ati Ekiti.

Nigbati awọn mejeji tẹ Ijẹsha do tan, nwọn tun pada lọ si Ile-Ifẹ lati lọ ko awọn enia wọn wa. Ajibogun mu ọgbọn (30) enia, Agigiri na si mu ogun (20) enia, gbogbo awọn enia na jẹ adọta (50). Olukaluku si mu awọn enia tirẹ lọ si ori ilẹ tirẹ.

**IBOJI AGIGIRI**

Iboji Ọba Agigiri wa ni Afin Ọba Ijẹbu-Jẹsha, nibẹ si ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti nfi Ọwa Ilesha jẹ oye Ọwa titi di oni-oloni. Awọn ohun-ini Ọba Ijẹbu-Jẹsha ti a le sọ diẹ ninu wọn niyi:

ITIMỌLE (Custody)—Iho ti nwọn nsọ alaigbọran sinu rẹ.

UGBERE (Prison Yard) Ọgba-ẹwọn tabi ibiti nwọn nko awọn arufin ti nwọn ti dajọ ẹwọn fun ni Oko-ọba.

Ọba Ijẹbu-Jẹsha nṣe idajọ fun apania. Igi Akoko ti Ọba Ijẹbu-Jẹsha fi npa awọn arufin ipania si wa nibẹ titi di isisiyi.

Ọgba Ọba fẹ to ọgọta oṣuwọn eeka (60 acres)

Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn oloye tirẹ ti o nfi jẹ oye ni Afin rẹ. Awọn Ijoye rẹ ti o nfi jẹ oye ninu Afin rẹ to adọjọ (150). Ninu awọn Oloye wọnyi, awọn oloye obirin wa ninu wọn pẹlu.

(KOI TI PARI)

# Alapara Ibadan

ALAPARA—Ẹ o jire bi o? Olotu?

OLOTU—Alafia ni a wa o. Ṣe nipa ọrọ asọti wa ti ọsẹ ti o kọja ni o tun ba wa tabi o ni irohin aladun kan lati fun wa?

ALAPARA—Ọrọ asọti wa na wa ninu ohun ti mo ba wa si ọdọ nyin ṣugbọn nko ni ri aye to bẹ ẹ lati joko pẹ titi lọdọ nyin loni nitori mo ni idiwọ kekere kan.

OLOTU—Iru idiwọ wo ni o ni?



ALAPARA IBADAN

* * *

ALAPARA—Ija nla kan ni o ṣẹlẹ larin awọn ẹbi wa, ti mo si nilati joko pẹlu awọn agbalagba lati yanju rẹ.

OLOTU—Iru ija wo ni, tabi kini o fa ija na ti o fi ka ọ lara to bẹẹ ti o fi fẹ wa ninu ijoko atunṣe na.

ALAPARA—Bi mo ba pe ki nsọ idi ohun ti o fa ija na fun nyin yio dabi ẹniti nfẹ idi araẹni sita, nitori ọran larin ẹbi ni, ni bi abuku kan ba wa ninu ẹjọ riro wọn, nko ni le sọ fun araiye gbọ, bẹ ẹ bi mo ba sọ idi ija na fun nyin nisisiyi yio di irohin ti gbogbo aiye yio fẹ gbọ bi a ti pari rẹ si.

OLOTU—O dara o, emi na fi ara mọ ero rẹ nitoripe ibajẹ ọjọ kan ko tan ni ogun ọdun. Ṣe o ko ni pẹ ki a to tun ri ra o?

ALAPARA—Pipẹ kẹ! A ki i hun agbọn ki a ma ki eti ,rẹ emi ti mo bere ọrọ pataki lọwọ nyin ti mo si sọ pe mo fẹ idahun rẹ, ti ẹ ko si ti fun mi ni idahun rẹ ha le dakẹ laifori rẹ ti na ki a to mu omiran sọ.

OLOTU—Ṣe ọrọ ibere rẹ nipa pe ọti wo ni mo ngmu tabi iyẹn kọ?

ALAPARA—Iyẹn na ni! Ẹ sa mu suru ki ntun pada wa.

OLOTU—Ọwọ emi na di pupọ nisisiyi boya ti o ba tun pada wa nigbamiran, a a ma a sọ yẹn.

ALAPARA Ẹ ṣe pupọ o, o digba ọṣe o.

OLOTU—Kabọ o, ipade wa bi oyin.

# IKỌ - FEE TI I DI ỌNA-ỌFUN ỌJỌ KANNA NI YIO DẸ

Maṣe jẹki ikọ-hihu, sinsin, didi ọna ọfun ti ikọlu Ikọ otutu tabi ikọ-fee fi ọjọ kan tabi oru ọjọ kan ba orun tabi agbara ilera rẹ jẹ laiko dan MENDACO wo. Egbogi nla-nla yi ki ṣe eefin, aberẹ-gigun tabi fifọn, ṣugbọn ninu ẹjẹ ni o nṣiṣẹ. bayi ni o ti ṣe de inu ẹdọforo ati awọn iho-ọna-ọfun. Akọlọ rẹ yio bẹrẹ si ran ara lọwọ lẹsẹkẹsẹ ni ọna mẹta: Ekini yio ṣe iranlọwọ a ti dẹ kẹlẹbẹ kiki ti o nfun ọ lọrun, yio si yọ ọ kuro. Ekeji Bayi ni yio si fun ọ ni anfani mimi kalẹ ati pẹlu irọrun pẹlu orun asunwọra. Ẹkẹta. O nṣe iranlọwọ didẹ-ikọ, mimi tipa-tipa ati sinsin. A ṣe ileri itẹlọrun ninu lilo rẹ tabi ki o gba owo rẹ pada. Ra MENDACO lọwọ apoogun loni.

# Ọba Agura Gbagura, Abẹokuta, w'aja

ABẸOKUTA.

GBUKẸ ni irohin kan kakiri igboro Abẹokuta ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandilogun oṣu ti o kọja yi nigbati nwọn tu ọfọ Ọba Alaiyeluwa Shobẹkun Keji Agura Gbagura, Abẹokuta, pe o w'aja nigbati o di ẹni ọgọrin ọdun l'aiye ti o si ti ṣe ọdun mẹrinlelogun lori oye.

Iyawo mẹdogun ati ọgbọn ọmọ ni ologbe Ọba na fi si aiye lọ ti nwọn ṣ'ẹhin de e. Nigbati ologbe Ọba Alaiyeluwa Adeọṣun Agura Gbagura Abẹokuta w'aja, ninu ọdun 1936 ni Ọba Shobẹkun bọ si ori oye. Shobẹkun yi si ni Ọba Agura karun ti o jẹ lati igbati nwọn ti tẹdo si Abẹokuta.

Ohun ti awọn ara ilu sọ nipa Ọba yi nipe, nigba aiye rẹ, abiwapẹlẹ Ọba ni iṣe, ko si ija, ko si ọtẹ, igba rẹ si tu awọn ọmọ Gbagura t'ile t'oko lara, atipe lati ọjọ ti o ti w'aja ni awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati awọn Minista ti nkọwe ibanikẹdun si awọn ọmọ ati ẹbi ologbe Ọba na.

Awọn ti ilu si fi ṣe adele-ọba ologbe na ti yio ma a mojuto gbogbo eto ti o nlọ ni afin rẹ ni Oloye Y. O. Lalekan (Osi Iddo) Shodipọ (Oluwo Iddo) Gbadamọsi Adedapọ (Badda Iddo) Sunmọnu Adewusi (Leragun Iddo) ati Alli Kassim. Nwọn si tun fi Oloye S. K. Adebayọ ṣe akọwe awọn adele-ọba ologbe na. Ọrun rere o, baba kabiyesi.


## Tarpaulin Industries (W. A.) Ltd.

**Ni awọn onişowo igbokun (TARPAULIN) Naijiria, ti nwọn ndabo Koko ati Ekurọ, itẹsilẹ fun Koko ati Ekurọ, ti nwọn ndabo mọto-akẹru ati awọn aṣọ igbokun miran.**

P. M. B. 2227
7 DOCKYARD ROAD, APAPA.

Telegrams
TARPIND Lagos








Published by Allied newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" odun kan—Eko sile mejọ ati kobọ mejọ (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S. M. Ademuyiwa 7 Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.